# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. III. No. 138. SATURDAY, MARCH. 7, 1925. 4d

**Declared Circulation 1,450 Copies Weekly.**

**White's Golden Female Tonic.**

A splendid Remedy for female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhœa (White's), Cramps Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A tendency to Miscarriage etc., etc.

**Made and sold only by** VICTOR WHITE, Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B. Not obtainable elsewhere.*

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.
OYINBO ***J. F. SICK***
Ọba Ilękę, Ile Ilękę, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilękę, orişirisi Ilękę wọnyi wa ni tita :—

Ilękę Oyinbo, Ilękę Rubber, Ilękę Olomi Wajì, Ilękę Onikẹkẹ, Ilękę Elẹjo, Ilękę Ayinrin, Ilękę Oniwõrò ati Fadaka, Ilękę Kerewu, Ilękę Jòjò, Ilękę Òlokuta, Ilękę Oloruka, Ilękę Ẹlẹranko, Ilękę Didan Yinrinyinrin, Ilękę Meremere, Ilękę Mọjọkun, Ilękę Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aşọ Işọ'ọşọ, Ẹrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni :— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# LEVER STORES LTD.

## THE PEOPLE'S STORE

---

## NOTHING NEW UNDER THE SUN

## BUT ALWAYS

# Something New

AT

# LEVER STORE

AND

# Nothing over 1s.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

PAKUTE GẸSI KO MA SI ẸNITI KO LE MU !

Olcgbo pa'mi-pa'mi o wọ̃ ni ọrọ ti a ...e sọ nigbati a gbọ ti ẹwọn ọdun mẹrin ti Adajọ Agba ni Kotu *Assize* ni Ibadan ju John Ogulesi si, fun jijẹbi ẹsun ti a fi sũn pe o ko owo ori ti Ijọba ni ki o ma gbà ni Ijẹbu Ode jẹ ; ni *Monday* ọsẹ yi la gbọ labari yi—ogun buru ilu kò dun !

OWO KO MA NFUN OWO LỌRUN O !

Ni ọsẹ melo si, Kotu Kantanyan ( *St. Anna's Court* ) yio di şişi fun biba işẹ lọ, a ...o pe Kotu na kò ni şaroye pe awọn ọmọ Ile-iwe Ita Tinubu npariwo si on ...eti nipa kike igbe wọn *A a, B b, C c*, ti awọn ọmọ na yio si ma jẹ ajẹgba bi ti Kọnkọ, lẹhin igbati a ba bẹrẹ ẹjọ riro nibẹ ; ...na kini, şe Ijọba mọ pe Ile-iwe yi wa nibe ki nwọn to gbọjẹgẹ ati kọ Ile-ẹjọ sibẹ ; ...na keji, ọga nta, ọga nra ni ọrọ na ; ọga ...i fi ọja ọga d'ọpọ, ibẹ ni Kotu si ba ...ukuru na: dajudaju ẹniti a ba l'aba la ...pe ni baba—o d'ọwọ̃ nyin o !

ỌLỌMỌ LA,
ỌRỌ ỌMỌ JA-NTO-JA-NTO.

Ko si bo ti ri ni Isin Isami ( *Baptism* ) ...a şe fun *Lady* Awẹlẹwa Miss Tharsilla ...mọ Ọgbẹni Theordore Harding a f'abẹrẹ-...e-ni-lore, a-ranşọ-ma-ran-ti'şọ̀ ati obinrin ...e Mrs. Elizabeth Harding, Ibadi-aran ti ...8 *Luther Street*, ( Mọşalaşi Olosun ) ni ...*Church* Aguda nla (*Holy Cross Cathedral*) ...ile yi ni iwọn agogo mẹrin ọjọrọ Sare-...ede ( Satide ) to kọja ; orukọ diẹ ninu ...wọn gbajumọ ti a pe si ibi ẹyẹ na leyi :—

Mrs. Sweety Hughes, Mrs. Geogetta Marsh, Mrs. Ọtọ Jones, Miss Grace Brown, Miss Modupẹ Taiwo, Miss Florentina Davies, Miss Esther Labinjọ.

Orukọ Onigbọwọ *Lady* na leyi :—

Ọgbẹni George Campbell ati Iya-afin Mrs. Nelly Campbell.

Nşe ni Ọgbẹni Harding ati iyawo rẹ Ibadi-aran fi'le pọn'ti, ti nwọn f'ọna ro'ka ni ọjọ Satide yi, ti gbogbo nkan şẹnure ti ọti " ayala " *Champaigne* olowo lori ati awọn ẹmẹwa rẹ nşan bi àgbàrá. Ẹ ku inawo o ! ẹ o jere ọmọ na ; yio si di irun di igba fun nyin.

IPADE TO LARINRIN.

Ranyin-ranyin bi agbayun ni Ipade ti a şe ni Ilupesi ni alẹ *Tuesday* ọsẹ yi fun ọrọ aladun ti *Prof*. Deniga, *Editor* " *Eko Akete* " sọ nipa ti ẹni wa Ologbe Ọgbẹni Dada Adeşigbin ; ãyàn ina titan di ni lọwọ diẹ ni akọkọ bẹrẹ, şugbọn lẹhin igbati ina ti wọ'le ti okunkun si parada tan ti a bẹrẹ ọrọ aladun yi nisisọ ni ọkan ko jọ'kan, irohin ko to afojuba ni alẹ ọjọ na jẹ o jare ẹnikeji ; lẹhin eyi ni Ọgbẹni Ayọ Ajala *A. Mus. C.M.*, ( *Lond* ) tẹ akanşe orin ti o ti şe lori dùrù pẹlu diẹ ninu awọn *Choir*. Ọrọ ti Alaga wa alẹ ọjọ na sọ, eyini ni Ọgbẹni H. S. Abiọdun Thomas, olohun-oyinmọmọ dabi ẹnipe ki o ma dakẹ mọ ; lẹhinna ni awọn Ọgbẹni diẹ sọrọ, awọn bi Ọgbẹni J. A. Adesanya, Ọgbẹni Bọla Cole gba'gi-mọ'lẹ Ọba.

Ọrọ ti Alasọye na sọ ka ni lara tobẹ gẹ̃ ti Ọgbẹni J. G. Holoway ti Ile "Ẹnuyami" ni Ọfin dábà pe ki a tẹ ẹ ni Ede Gẹsi ati Ede Yoruba ki a si tan kakiri fun anfani gbogbo awa ọmọ *Africa* ati ẹlomiran, lọgan ni Ọgbẹni C. Ọlayẹmi Blaize Onişowo ti

Ile ' Igbore " ni Ebute Mẹta gbe imọran yi lẹsẹ ti Ọgbẹni Popius John si kinrin rẹ lẹhin, ti gbogbo ipade si gba imọran na t'ọmọde t'agba.

Alaga dupẹ gidigidi fun àbá bayi ṣugbọn o wa ni wa niran owe kan to sọ pe " Owo ni ti on ko ba si ni'le, ki ẹnikẹni maṣe damọran nkan kan" ; lọgan ni Ọgbẹni Akin Adeṣigbin si jọhẹn lati tẹ iwe na gẹgẹbi ifẹ Ipade, l'ọfẹ. Nigbati Alaga si jihin yi fun Ipade, nṣe ni atẹwọ lọ titi, ti ariwo ayọ si sọ lálá.

Ọgbẹni A. B. Laotan si sọrọ alàye kan si ọrọ na, ile kun, ọna bò lalẹ ọjọ yi.

Alufa J. R. Williams ti Ijọ Alaribọmi (*First Baptist Church*) damọran pe ki Alaga yọda fun Alasọye ki o sọ ọrọ aladun ti o ka si Ijọ l'eti ni ti Gẹsi, l'Ede Yoruba ni ṣókí fun anfani awọn ara wa ti ko gbọ "Kọnkọ-biliti ;" lọgan a ṣe bẹ o si jẹ itẹlọrun olukuluku.

Ọgọrọ ni awọn to wa, awọn ti a si ṣakiyesi leyi :—

Alaga Ọgbẹni H. S. Abiọdun Thomas Olori awọn Ẹgbẹ Akọwe Ọba ti gbogbo Nigeria (*The President of the Nigerian Civil Service Union*) awọn isangbe rẹ :— Ọgbẹni Anthony B. Laotan, ti Ile-òwò Oyinbo Odo Ọya (*Niger Company*) a-bi-gege àrà lọtọ, Ọgbẹni Akin Adeṣigbin A-tohunṣe-masiregun, Alufa A. Adeniji Puddicombe ti Ijọ Ararọmi (Ararọmi *Baptist Church*) Atẹrẹ-kanri, awọn Ọgbẹni J. K. Coker, J. B. Coker, J. H. Glover Willoughby, J. G. Holloway, Alufa J. R. Williams, a-fi-dudu ṣ'ọla, C. Ọlayẹmi Blaize, a-pọn-b'epo-rẹ, Ọgbẹni H. Antus Williams, Ọgbẹni T. I. Kester (*of the Colony Police*) S. A. Johnson (Ifẹ Ọlọrun) Augustus Scott "*Sir Walter*," E. M. Awobiyi, Akilapa-ki-lẹsẹ-bi-ogidan, E. J. Ọpẹbi, Olufẹmi Blaize, A. Ọmọtẹṣọ, Moses A. Johnson, E. P. [illegible]aiwo, Rev. I. O. Oyekunle, John Mohammed Beyioku Ajiṣafẹ, Ọgbẹni S. Ayọdele Thomas a-bi-jigi oju yẹnrẹn-yẹnrẹn, Ọgbẹni S. A. Braithwait ọkọnrin kọkọbọtọ, *Editor Nigerian Advocate* Ọgbẹni J. E. Ṣolade Solomon ti *P.W.D.* (Eko) Ọgbẹni D. Ayọdele Bright Ọlọyaya ọkọnrin, Ọgbẹni Orioye, Ọgbẹni Idowu, awọn Iya-afin Flora Ibidapọ Elliott, Aniwura, Mrs. King, Mrs. Elizabeth D. Faro Williams, Mrs. Louiza Allen, Ọgbẹni S. S. Durosinmi Adu-ma-dan, Akindele Ajayi, Omidan (Miss) Ẹbun Adeṣigbin Awẹlẹwa, Lande Adeṣigbin ati bẹ̀ bẹ̀ lọ́. A dupẹ gidigidi lọwọ Alaga fun wiwa to wa lẹhin igbati o jẹ pe akoko ti wọ'mu ki a to sọ fun, nitori iṣẹ Kotu ni Ibadan ti o di Ọgbẹni Adedapọ Kayọde Lọya a-mubina lọwọ, ẹniti o jẹ ọhẹn ati ṣe Ipade na, ti o si fi wáyà ṣọwọ si wa lati Ibadan, lati la'di aile tete de rẹ.

A si dupẹ lọwọ Ọgbẹni H. Antus Williams fun fifi han ti o fi Alaga han ipade ati awọn isangbe rẹ. A si dupẹ lọwọ Ọgbẹni N. A. Ṣolade pẹlu fun iṣẹ to ṣe. Ati ẹnyin ọrẹ ti ẹ wa ba wa ṣẹhin Ologbe.

Bẹ si ni a dupẹ lọwọ Ọgbẹni Ayọ Ajala ati awọn ọmọ ẹhin rẹ fun bẹbẹ ti nwọn ṣe lalẹ ọjọ na.

INA O ! ORO O ! !

Mọto akẹ́rò ti Ọgbẹni Ọtun ti a mu lọ si Ibadan ni lọlọyi, gbina nigbati o de apa Ọtà ; mọto na bo wọn mọ'lẹ batakun bi igbati Abawun Okun iba bo enia mọ'lẹ ina na si *roast* awọn enia meji bi ẹni *roast* Adiẹ, tobẹ ti nwọn fi ṣe alaisi.

Nitotọ " larin iye awa mbẹ ninu iku.

Ki Baba ṣọ ni.

OLODUMARE BABA TOTO,

A WO'LẸ O, A BA BURUBURU.

Pẹlu inu didun la fi sọ ti Ijọ́ Isin Ọlọrun kangọṣọ Mimọ (*African Unitarian Church*) ti awọn bọkinni Olufọkansin kan ọmọ *Africa* da silẹ ni Eko nibi ni ọjọ die sẹhin.

A o tun ma jihin igbati *Church* yi yio bẹrẹ si ijọsin fun Baba ni Ẹmi ati ni otitọ.

" Kiṣe nipa ipa, bẹni kiṣe nipa agbara bikoṣe nipa ẹmi mi ni Oluwa awọn Ọmọ ogun wi."

## ELEBUTE, MELO MELO E.

[ Lati owo AKIRIMANU ]

Si Oniwe-irohin "*Eko Akete*"

Mo juba o,

Ni Bode (*Customs*) opolopo yio se akiyesi pe awon apako meji ti Ijoba ti fi si ara ogiri lati ma le (*Notice*) iwe akiyesi mo ti kuro nibe, ngbati a fi imu finle wa idi oro na a gbo pe Oyinbo kan ti awon npe ni W. F. Wadham (*Wharfanger*) Elebute lo se ise yi, nitoripe o da ni enipe ko ni ise pataki kan se ju ki o ma sure kiri ni ogba *Customs* lo a si gbo pe ise re ko ju ise Elebute lo eyiti oga awon lebira Bode le se daradara. Apako mejeji wonyi ti wa ni ara ogiri yi to ogbon odun ti gbogbo ilu ti ngbadun re tomode tagba. awa Yoruba lo npa lowe pe eniti o ba mo wura la nta fun a gbo re Oyinbo yi ko mo "A" ni ese malu ninu iwe. Bi o ti jepe labe ogagun Koleto Adams ni Elebute lo gbe wa a o be ki o ma sai fiyedenu ki o fi awon apako miran si fun anfani tomode tagba. Enu kekere ko, lo ya wa ngbati a gbo pe Oyinbo W. F. Wadham yi owo osu re je £41. 13. 4. beni Ijoba nso pe owo kosi, beni bi a ro gbogbo owo lebira Bode ro boya lo to ti Oyinbo yi nikan, ise Oyinbo yi je ise ti lebira ki lebira le se, kini anfani irufe Oyinbo bayi ni oju ti wa, o dabi enipe Ijoba nna owo ilu ni inakuna ki se ife inu wa lati se ibaje fun enia, sugbon a ko le ri otito ki a ma so. Sibesibe Ijoba nfe ka ni igbagbo pe owo kosi lati fi se ile Alarun to. wa ni Ereko (*Ereko Dispensary*) sugbon Ijoba ri owo na lori iru Oyinbo ti a daruko re yi. Opolopo yjo wipe kini kan *Akirimanu* nipa inawo Ijoba beni mo rope bo se toro lasan lo nti apo mi jade si apo Ijoba mo ni enu lati so oro; bi enia dudu egbe mi ba se ohun ti ko to a o wi fun anbosibosi awon Oyinbo, nitorina ki Elebute lo ba ara re nile ki o si ma dupe pe Olorun fi ilu *Nigeria* bo ni asiri ni ki o si ma ranti pe opolopo ti o le fi ese ko iwe wa ni ilu won to nrin gbara kiri.

## B'IKU ILE KO PA NI T'ODE KOLE PANI

Awon Hawusa lo npa lowe pe :—" Beri-beri ba ka beri ka beri banza " iyen nipe bi awa eda ba akilo fun enia pe iwa aseju ko dara bi ko ba si gbo igbehin re a si wa di asesa. Gegebi gbogbo wa ti mo pe eranko la nde si eranko benani a se akiyesi oniruru iwa ti inu mi ni ngo se to ngbile larin ilu wa papa lodo awon olori ati alagba wa; bi Ijoba ba nfe mu nkan pataki kan to le fa owo wo fun won wa si arin ilu ogbon ele ni nwon ma nfa awon alagba wa mora ti nwon o si tan won jere pelu ileri pe awon yio fun won ni oye bi C.M.G. tabi O.B.E. lori oye wonyi ni awon enia wa yio ma yo senken pe nkan ti se enure fun won; ohun kan ti o mu wa sope "b'iku ile ko pani tode kole pani" ni akoko kan ti awon Ijoba ngbero lati se ofin titun fun ile awa enia dudu boya ofin ti iba mu ki awa papa di eniti iba ma pada haya ile wa lodo Ijoba se akoko na se konge igbati Oloye Oluwa ngbero lati gbe ejo re lo sodo awon agbagba meta korogbakorogba ni ojutaiye ni ilu Oyinbo tani ko mo iru ete ti awon enia wa pa tan ni akoko na lati le ba ejo yi je ni ilu Oyinbo fun itelorun Ijoba ki nwon ba le ma pe won ni Mista so so & so C.M.G., O.B.E. loni a dupe lowo Olorun pe ika lo nrojo ika ko lo ma da, Oloye Oluwa gba are bo ninu eyiti gbogbo wa nje anfani re ni gbogbo ile enia dudu ni apa ihahin. Benani ti oro Oba wa Eleko ri bi Gomina wa agba tile so pe Eleko se on nipa pe ko lu agogo, awon tani iba so pe nitoto ni, sugbon iyen ko to ija ki Gomina mu suru titi Oloye Oluwa yio fi pada de pelu orbufo re Ogbeni Herbert Macaulay nigbana ki nwon wa so ti enu won kaka be se sunasi ni awon alagba wa nse kita pe ko ni se oju awon ki Gomina fi Eleko si ipo re, lode ti oni tani ko ri dajudaju pe iwa awon enia wa lo ndun gbongbon bi agogo ninu oro Eleko pelu Gomina lona keji gbogbo ilu gbarajo ko iwe ebe kaka ki Gomina fi esi ire ebu lo ko tile to nbu t'omode t'agba lehin ti a ti mu suru tan ni awa ri pe awon majekitenisunwon enia wonyi lo ko si abe oro na, sibesibe se ki se *Nigeria* ni Oloye nla Hugh Clifford ko je Gomina si ati pe bi on papa ba je omo Oba ilu kan ti Olorun si gbe si ipo Oba dipo baba re ti awon Oyinbo ti baba re pe ko wa jeun si nfi oni daduro fi ola ro ejo mo lese bawo ni yio ti ri lara Oloye nla Hugh Clifford, awon agbalagba lo npa lowe pe "a lo tahun abo tana e" nje be ha ko ni oro Oba wa Eleko pelu Oloye nla Hugh Clifford da loni, are tile ti mu gbogbo enia pe se onigbagbo ni Gomina yi tile npe ara re kini se? Eleko ko pa enia, ko ta eru, ko di ote si Ijoba, ko jale, ni oju ti awa oro Eleko yi ko to ohun ti iba mu ki gbogbo aiye ma bebe lati odun gboro yi wa ki Gomina wa ma pekelu oro na, ki a to mu enu kuro ninu oro na a o tun so eyiti a rope o to "ete awo ni ete ogberi" iyen ni ti awon enia wa ti nwon fi ake ko ori pe itiju ti awon papa ni, mo gbo fenren pe okan ninu awon alagba wa gbojugbaiya lo si ilu kan ni odun to koja ti o si nfe da si oro Oba won ni ilu na, a gbo pe awon agbagba ilu na so agbeje mo ni idi nipa fifi oro wonyi gun lara "Enyin mo oro Oba so ni Eko ni e gbe Oba yin ko si ori igi" oro na je ohun ibanuje fun alagba yi tobe to fi sure wa'la kitakita pe o to ge oro Oba wa Eleko to so nitori eyi ni ase wipe "ete awo ni ete ogberi" sugbon awon to ni ori ti ko ni fila wonyi tun yi lokan pada, boya lakoko ti gbogbo oro na wa su gbogbo aiye okan won le ro lati

ba Gomina sọrọ pe "ẹtẹ awo ni ẹtẹ ọgbẹri" nitotipe ko dara ki gbogbo ilu ma yangan Ọba ki awa fi o jẹ olu ilu *Nigeria* ma le fi owo sọ aiya pe:—Ẹru Ọba ni mo ba Eleko, Ọlọrun ti tẹlẹ ohun gbogbo.

## BI A BA NBU ẸTU ORI A MA RO AWO.

Ninu esi ti *Eko Akete* fi si ọro Oyinbo kan to pe ara rẹ ni F. A. Day o sọ kasikan ọrọ otitọ fun awọn Oyinbo miran lati le mọ pe bi a ba sọ pe Enia Dudu njale ko to ti awọn Oyinbo funfun nitoripe ninu iwe Irohin ilu wọn ọmọ jaguda pọ to wọbu nitoto awọn enia wa jẹ ka sọ ireti nu, a ti ri ọpọlọpọ Oyinbo funfun to jẹ pe iṣẹ de ni nwọn ba wa si arin enia dudu ninu awọn onişowo Eko yi omiran ṣe tobẹ igbẹhin rẹ şişe lo salọ tani ko mọ ogunlọgo wọn kakiri pe ogbóle ni nwọn jẹ, lakoko kan iwa abosi yi ngbilẹ to bẹ ti awọn onipo nlanla ni igboro Eko yi na fi pa imọ po lati ma jẹ owo (*No 1 Letter*) fi aşiri wọn han. (*White man take it, blackman steal it*) bi F. A. Day ba nsọ pe awọn enia dudu akọwe ko gbọ Gẹsi melo ni Oyinbo to le sọ ede Yoruba daradara şe bata ko jẹ ki a mọ agesẹ ninu Oyinbo bi o ba jẹ pe ki awọn Oyinbo to ma bọ wa si ilu wa yi nwọn ni lati dan ọpọlọpọ wọn wo, dajudaju ebi iba pa pupọ ku si arin ita gbangba, njẹ ninu awọn Oyinbo funfun na kọ ni Lọya wa na ọwọ gan to si ni ko tu ọrọ yi wẹwẹ fun on (*Please spell the word conscience*) kabokabo ni arale mi bẹrẹ si sọ ni Kotu to bẹ ti oju fi nti enia pe Oyinbo funfun sa ni eleyi, ko mọ ede ilu iya rẹ, ọrọ F. A. Day fihan gbangba pe ko ni ẹkọ bi iwa enia dudu ko ba dara fun Day kinişe ti ko pada lọ si ilu rẹ ki o ma lọ ru edu bi awọn ẹgbẹ rẹ. o to o yẹ ki Day dupẹ lọwọ Olorun pe on ko si larin awọn to nu bata ki nwọn to ri kọbọ mu lọ ra onjẹ, (*If F. A. Day is a negroephobist why on earth this high winded European cannot remain in his country*) bi enia ba wa idi awọn Oyinbo bẹ yio ri pe enia lasan kan ni nwọn jẹ nitori na a fi eyi şe kilọkilọ fun Day pẹlu awọn alabaro rẹ.

## ỌGBỌN AGBỌNTỌN IJA LO NDA SILẸ.

Ni igbesi aiye wa ẹnikẹni to ba nfẹ şe olori yio kọ fi ara rẹ sipo ọmọ ẹhin ti gbogbo enia le ma ti sihin sọhun ati pe nipa suru rẹ yio pada di olori şugbọn ti inu mi ni ngo şe ati pe ọgbọn ori mi yatọ si ti awọn ẹlẹgbẹ mi şişe ni iyẹn ma nba nkan jẹ. Ni koi ti pẹ yi ni a gbọ pe awọn kan ko ara wọn jọ pe igbagbọ wọn pọ to bẹ ti nwọn ko jẹ lọ ogun bi aisan tabi aile ara ba de si wọn, awọn wọnyi ni a npe ni (*Faith Tabernacle*) lati igbati awọn onigbagbọ titun wọnyi ti bẹrẹ a ko gbọ işẹ iyanu pataki ti nwọn şe, şugbọn a mọ dajudaju pe ni ọjọ ti enia kan ba ni lati lo ogun si aisan ni ọdọ wọn ti wọn ko si fun ni aye lati şe ti oluwarẹ ba si şeşi ba bẹ ku si wọn lọwọ laisi tabi-tabi awọn papa mọ pe eşu yio şe Charlie. Şe bẹni a gbọ ti awọn ọmọ lẹhin Bişọpu Işola gbega tobẹ ti nwọn nsọ pe oye gbogbo ti Bişọpu yi gba jẹ iru oye ti Jesu Kristi gba ati pe Bişọpu wọn na si le şe bi Jesu Kristi ti şe ni ode aiye ni akoko Rẹ dajudaju tani ko mọ pe apọnle lasanlasan ni gbogbo ọrọ wọnyi jẹ? Bi a ba şepe agbara ti Jesu Kristi ni ti o si fi ola oju awọn afọju ti bọ si ọwọ awa ẹda olobinrin mẹrin marun wọnyi kini ha şe gẹgẹ bi ojişẹ Ọlọrun ti a ko şe anu fun awọn ogunlọgo afọju to pọ to jiga ni igboro Eko yi tabi Jesu Kristi ko kọ wa pe ki a ma fi agbara wa ran ara wa lọwọ bi? A o dẹkun ọrọ wa ti ọsẹ yi nipa ọrọ oye ti a jẹjẹ pe a fẹ sọ pẹlu inudidun ni a fẹ fi sọ pe awọn agbalagba ti ti ẹsẹ bọ inu ọrọ na nipa bẹ a ko fẹ ma ki ọrọ si wọn lẹnu; njẹ bi awẹ ti nkankun ni arin onigbagbọ bẹ nani larin awọn Imale, ki Ọlọrun ma şai fi ire to wa ninu rẹ kẹ gbogbo wa.

Emi ni tinyin nitoto,

AKIRIMANU.

---

## DADA ADESHIGBIN OF BLESSED MEMORY

*By Clipeus.*

An Oration was delivered by Prof. Deniga at the Ilupesi Hall on the late Dada Adeshigbin the 3rd instant at 8.15 p.m.

Mr. Deniga gave a resume of the life of the deceased with characteristic lucidity.

Dada Adeshigbin was born at Owu in the year 1865.

Hardly anything is known of his early life except that he was educated at the Breadfruit School, Lagos and later on he was apprenticed to a famous tailor of those days who was very strict with his business, a disciplinarian of a business man. He adopted the motto "Business before pleasure", after he became free from apprenticeship. He was the sole agent of the "Singer" Sewing Machines, and so conscientiously did he do his duty that till the time of his deceased he was sole agent of the "Singer" proprietor in America. He was an ever-ready man in all charitable works that he made nothing of the most strenuous exertions even in Church matters. He would undertake a tour throughout the northern parts of Nigeria where the interest of the Church is concerned. He gave liberally He worked diligently, faithfully, unstintedly. He would do many things that pertain to his business, free of charge, without ostentation. He obeyed his Saviour's injuction, "When thou givest thy alms, let not thy left hand know what thy right hand doeth," to the last breath.

He was a peculiarly reserved man of sterling honesty and great kindness.

He was personally known to writer and by no means a stranger to the community. He was one of the principal founders of African Bethel Church. At the time of his death, there was a partial eclipse of the moon at 11 p.m., on February 8. "Seest thou a man diligent in his business? He shall stand before kings." Mr. Adeshigbin was diligent all through.

Mr. Adeshigbin's gone, plucked away like ears of corn fully ripe to the realms above. The distinguished lecturer ended with the well-known portion of Holy Writ in the book of Revelation, "I heard a voice from heaven, saying unto me, write from henceforth blessed are they that die in the Lord (yea, saith the Spirit) they rest from their labours.

The Oration was then thrown open for discussion.

It was at length resolved to form a committee to undergo expenses for printing the oration in pamphlet form both in English and Yoruba. Mr. Akin Adesigbin rose to the occasion and offered to print the pamphlets free of cost and his offer was cheered by the audience.

It was a glorious affair. Both English and Yoruba are worthy of the lecturer.

CLIPEUS.

## IN MEMORIAM.

In ever loving and affectionate remembrance of my late beloved niece.

MRS. VICTORIA RUTH OLUBUNMI EUBA

(Eldest daughter of Mr. & Mrs. H. A. Williams, Offin Road).

Who departed this life on the 8th March, 1923.

Sleep on, beloved, sleep and take thy rest;
Lay down thy head upon thy Saviour's breast;
We love thee well; but Jesus loves thee best—
Good night! Good night! Good night!

AUNT KOFO.

## IRANTI.

Ni iranti aburo ati ẹgbọn wa ọwọn

MRS. ANGELINA B. CONDE

(alias KEKERE)

Ẹniti o mi ẹmi ikẹhin rẹ ni opopo Bamgboṣe l'Eko ni ijọ 5 oṣu *March*, 1920.

A o pade nikẹhin,
Lọd'Ọlọrun Ẹlẹda wa
A o si wa n'iṣọkan pẹlu Rẹ
A lọ ma ni igbagbe
Sunre. Sunre. Sunre.

F. PINKETT PAUL,
ERAS. J. REIS.

[1]1, Bamgbose Street,
Lagos.

## Thanks for Sympathy.

Mr. Ishola B. Tijani Byron on behalf of himself and family begs to return his sincere thanks to all kind friends here and abroad; who in diverse ways have expressed sympathy with them for the irreparable loss the family was called upon to mourn on Tuesday 24th instant, through the death of his beloved sister Madam Adijatu Abẹkẹ.


## White's Golden Male Tonic.

(DOUBLE-STRENGTH)

Whenever a women has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. *White's Golden Male Tonic* (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

**Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

*The Reliable Dispensary, 41 Offin Road, Lagos.*

N.B. NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.

SHAKE THE BOTTLE.

## AREMỌ FUN ỌKUNKIN

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo Arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

N.B.—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo mejimeji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price ten shillings (10/-) per bottle.

## White's Convulsion-Killer.

(FOR BOTH CHILDREN AND ADULTS.)

**Sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

**The Reliable Dispensary.**

**41, Offin Road. Lagos.**

DIRECTIONS:—For adults one Tablespoonful every halfhour until the fit is gone. As a preventive, one Tablespoonful every morning before food. For Children, one desertspoonful, in the same manner.

"SHAKE THE BOTTLE."

## EGBOGI AIPERI

(Fun Ọmọde ati Agbalagba.)

Akajuwe:—Fun Agbalagba, Ṣibi ti a fi njẹ iresi meji-meji ni ababọ Wakati, titi aiperi na yio fi fi oluwa rẹ silẹ. Fun ọmọde ṣibi kọkan bakanna.

Ki Aiperi ma ba ṣeni:—Fun Agbalagba, ki a ma fi ṣibi meji-meji tẹlẹ inu lọrọ. Fun ọmọde ṣibi kọkan. Ki a mi igo na daradara ki a to mu egbogi na.

PRICE FIVE SHILLINGS (5/-) PER BOTTLE

EKO AKETE

EKO, SATURDAY, MARCH. 7, 1925.

## POROPORO LA NRỌ 'FA ADITI.

Titẹnumọ ọrọ kan nigbagbogbo fun rere ati anfani ẹnikan, to si dabi ẹnipe Lagbaja, Tẹmado, tabi Lakaṣegbe ti a nsọ iru ọrọ bẹ fun, ko ṣe ni ni pinṣin imu, eyini ni pe ko p' ẹkẹ lu imọran na, titi ohun alebu ti o le mu abamọ wa ba oluwarẹ si ba dandan, ko ni ṣe ẹbi ti ẹniti a wi fun ti ko gbọ yi le diru ẹnikẹni, kaka bẹ oluwarẹ lo ma pada jẹbi ikilọ na, yio si fi iwa rẹ sọ ara rẹ loruko "Alaṣeju to np' ọkọ ni baba"; irufẹ orin yi lo si yẹ ki a ma kọ fun iru Lamọmọ to nmọ egbo ojugun na pe "Mo wi fun ẹ de'po, o ku s'ọwọ rẹ."

Iṣu ti a ba tẹnumọ ki jona bọrọ bẹgẹgẹ ni ọrọ ti fif'oju s'ọna ti Ilu Eko nfoju s'ọna *Edward* Arẹmọ Ọba. Ki a wo oke, ki a si tun wo odo, a ko ri ipalẹmọ kan danindanin ti a ko ri iru rẹ ri ti a nṣe nisinsinyi, ko si pe awọn Musulumi tabi awọn Kiriyo nlu gbagba fun "aṣọ ẹbi" lorişirişi, ti a o fi ṣe fuja fun pipade Arẹmọ na.

Ẹnyin enia wa, ẹ ko tilẹ dorikodo diẹ ki ẹ si woye? O ti pọ to nisinsinyi ti awọn Ẹgbẹ Tunluṣe. Awọn Ẹgbẹ Bombata (*Nigerian National Democratic Party*) ti ṣe arakuyamu ipade wọn ni'le Alari Ogun (*Glover Memorial Hall*) l' Ẹhingbẹti? O ni idi nitoripe ti ko ba ni idi, obinrin ki jẹ Kumolu: inu awọn ẹgbẹ na ha le dun bi ki nwọn ma ti ma ku s' ọtun ku s' osi, ki nwọn si ma bọ si 'le bọ so 'de bi ọkọ iyawo nipa ipalẹmọ ti dide Arẹmọ na? Bi inu ko dun bi igbẹ ni 'lu ri; lati ọjọ ti Ijọba wa nibi (*Our Local Government*) ti joye lamọmọ ti nmọ egbo ojugun, nipa *Committee* aluṣi ti nwọn ni nwọn yan fun itọju ẹyẹ afojusọna na kọ ni gbogbo rẹ ti di ẹti? nigbati Ijọba ti joye tolotolo to nyinbọn idi nipa iwa aifini pe ni aif'enia p'enia to mu ara oko san ibantẹ wọ'lu kọ ni awọn Ẹgbẹ yi ti takete ti nwọn si nwo wọn? Aṣẹṣẹ jade akan, a ko mọ 'bi to nlọ.

Tani iba ni ẹjọ awọn Ẹgbẹ Tunluṣe y ko jare? Kosi; tani iba jẹ kunmọyo ki ẹ da awọn Ẹgbẹ na l' ẹbi itakete bayi? A koi ti ri oluwarẹ. Nigbati ẹnikan ba nhuwa bayi ni ngo ṣe nkan mi, papa ohun ti o jẹ mọ ọrọ ilu, ti ki ṣe ẹru ẹnikan ṣoṣo tabi ẹru awọn enia suru diẹ, ti a ko si fẹ pe ilu bo ti tọ ati bo ti yẹ lati jumọ ru ẹru na, ẹlẹya ati itiju ti oluwarẹ ba ri ninu iwa igberaga to nṣiwaju iparun yi, yio fi ṣe ti ara rẹ ni, nitori a wi fun de'po lati ṣe atunṣe ohun ti o le mu ogo, iyin, ati idupẹ ba Olori ilu na, ti o ba ṣe ara rẹ ni IRANṢẸ awọn ara ilu, ti ko si ṣe ara rẹ ni Abata to takete bi ẹnipe ko b'odo tan. Ni ipari ọşu yi ni a gbọ pe Arẹmọ yi yio gbe'ra sọ, ti yio fi ilu Oyinbo silẹ; titi di bi a ti nkọwe yi, koi ti si pe Arẹmọ na yio ba Olori tiwa na nibi gẹgẹ bi o ti tọ suna, Ijọba joye ẹniti o wa ọrun ki si kikọ lati ṣe ifẹ ilu, ki gbogbo rẹ le bọ si ẹtọrọ̀rọ̀, bẹni Bibeli sọ fun ni pe ẹniti a ba nba wi, tabi ti a ba nşun leti lemọlẹmọ ti o ba si wa ọrun rẹ ki, yio ri aidara tabi iparun lojiji laisi aṣetun. A ko tọrọ aidara tabi iparun fun Ijọba rara; gbogbo ọrọ ti a si ti nsọ bọ lati ọjọ gbọrọ yi wa, ko ju pe ki nkan le gun rẹgi fun Ilu ati fun Ijọba lọ.

Ninu gbogbo iwa ati ọrọ enia, o yẹ gidigidi lati ranti nibikibi gbogbo pe "Igberaga lo nṣiwaju iparun," ẹtẹ lo si ngbẹhin alaṣeju.

Nitorina ẹnyin Ilu, ti Ijọba ko ba tilẹ ba nyin sọrọ yi, ki ẹ maṣe tẹ ara nyin nipa jijẹ Oye Ṣọbọṣọla. (Ṣugbọn iyẹn ko ni di wa lọwọ lati mu ilu ṣe ẹyẹ to tọ fun Arẹmọ Ọba na) King.

Ki ẹ si mọ pe ẹn'ti a ko pe, to wa tojubọ, Oju lo nya!!!

A BOON TO BUSINESS MEN.

Type-Writers of different Brands e.g. Barlock Underwood, etc. in good condition, on sale.

Prices reasonable to the man in the street.

Terms:—CASH.

Apply to the Editor.

## EKO ATI AWỌN ONIFILA-FUNFUN.

*Copyright.*

[ *Lati ọwọ* ATARI-AJANAKU. ]

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Nipasẹ ọrọ Eko ati awọn Onifila-funfun ni a sọ bi ilẹ bi ẹnu li ọsẹ ti o kọja, ni ede Gẹsi. Ohun ti o jẹ ki a sọro pupọ tobẹ, ati ni ede Oyinbo ni wipe, "ọmọ ina ni a nran si'na!" Ede Oyinbo ni nwọn fi kọ ikọkukọ ti Ọlọla Kitoyi Ajasa dà sinu Iwe rẹ lati inu Iwe-irohin kan ti a npe ni *African World*, ni Ilu Oyinbo; nitorina ni a ṣe ro wipe o yẹ ki awa na fi ede Oyinbo dahun, papa ki Oyinbo ti o tẹ Iwe na si Iwe-irohin rẹ ni Ilu Oyinbo le ri esi wa ka daradara l'aisi ogbufọ tabi gbẹde-gbẹyọ.

L'aisi ani-ani, ọlọtẹ kan li Eko ni o fi Iwe na ranṣẹ si Ilu Oyinbo fun titẹ, nigbati nwọn si tẹ ẹ tan, Lọya Ajasa yonbo rẹ, o si kan sàrá si ẹniti o kọ ọ wipe, gẹgẹ bi nkan ti ri ni ilẹ yi gãn, ni o wa inu Iwe araınu na.

A ko le sọ gbogbo isọkusọ ti o wa ninu Iwe na tan, bẹni a ko le sọ gbogbo idahun wa ni ede Oyinbo ti o wa ninu "EKO AKETE" ti Satide ijẹjọ nitori o gun pupọ julọ; ṣugbọn niba ṣoki ni a o sọ ọ ni ọsẹ yi, papa, fun anfani awọn enia wa ti ko gbọ "agirá," iru eyiti a ju ni ọsẹ ti o kọja.

Ogboni "Akowe alagba" ti o sọrọ ti a ko si i lẹnu na wi ninu Iwe-irohin ti Ilu Oyinbo, *African World* wipe, ko si edekoyede kan larin ilu nipasẹ ọrọ ilu; o ni ohun kan ṣoṣo ti o nmu ariyanjiyan wa ni wipe apakan ilu nfẹ ẹnikan ti ofin ti da l'ẹbi ẹṣẹ kan ri, ki o jẹ aṣiwaju, apa keji ko fẹ. O ni Ijọba pẹlu awọn Onifila-funfun ni aṣẹ ilu wa lọwọ rẹ, ati wipe gbogbo awọn Onifila-funfun ni a ti fi di elekuru lati wọ Ẹgbẹ ilu pataki kan, *Democratic Party*, Ẹgbẹ nla ti alakọri ti a nsọrọ rẹ yi ni ko ni itumọ ni ede Yoruba, ati wipe awọn aṣiwaju inu Ẹgbẹ na ko tilẹ gbọdọ sọ itumọ rẹ fun awọn Ọmọ-ẹgbẹ, ki orò ma ba gbe wọn. O ni *Chief* Adamọ Akẹju Ọbanikoro nikan ṣoṣo ni Oloye ti o jẹ akọni, ti o si gbọn pupọ-pupọ ju awọn Oloye ti o kù lọ, ati wipe gbogbo awọn Oloye iyoku ni o si fowo rẹ nitoripe nigbakugba ti Ijọba ba bere, ni Ọbanikoro ma nfi oye ofin ati aṣa ilẹ yi, eyiti o mọ pupọ ju ẹnikẹni lọ yé Ijọba. O ni, ohun ti o si jẹ ki ọpọlọpọ enia ma bu Ọbanikoro ni kikọ ti o kọ jalẹjalẹ lati jẹ ki ẹnikẹni fi on di elekuru lati wọ ẹgbẹ-k'ẹgbẹ ni ilu.

Onisọkusọ yi tun sọ wipe, ni akoko kan, nwọn wo ile Eleko, nwọn si tun wo "Afin" Ọbanikoro, nitoripe Eleko pẹlu Ọbanikoro jumọ kọ lati lọ bẹ Gomina nitori ẹnikan ti Kotu fi si Ẹwọn ni ilu; ati wipe, ni akoko Owo-omi, ẹhin Ijọba girigiri ni Ọbanikoro wa: o ni, lati igbana lọ ni ilu ti korira rẹ, gẹgẹ bi Musulumi ti korira a-b'irù-wéreke lori irẹsi!

Diẹ ninu isọkusọ ti alakọri yi sọ niwọnyi, ti Lọya Ajasa si gbe e l'ẹsẹ ninu Iwe-irohin rẹ ti ọjọ kẹfa oṣu ti o kọja wipe, bi ọrọ ti ri ni ilẹ yi gãn ni yẹn, ti o si tun sọ ninu Iwe-irohin rẹ *Nigerian Pioneer* ti ọjọ kẹtala oṣu ti o kọja wipe, nigbati awọn kan ba ọrọ pataki ti o ndun wọn lọ si ọdọ Balẹ Ilu (*Resident of the Colony*) ni aipẹ yi, *Resident* bere itumọ *The Nigerian National Democratic Party* lọwọ wọn; nigbati nwọn si sọ wipe awọn ko mọ ọ, o gbe Iwe Gbede-gbẹyọ (*Dictionary*) jade, o si sọ itumọ orukọ Ẹgbẹ na fun wọn, o si wipe, iru Ẹgbẹ bẹ lodi si ọrọ ti nwọn ba wa si ọdọ on. Ti o ba jẹ irọ, Ajasa l'o pa a!

Esi ti awa fi si gbogbo ọrọ rederede wọnyi ni wipe:—(1.) O ṣoro ki ẹnu gbogbo enia ti o wa ni ilu patapata to le ṣ'ọkan lori ọrọkọrọ; nitori bi, ẹniti o nfẹ ire ilu ti wa, bẹni arijẹ ninu ọtẹ si wa pẹlu, ati wipe, ẹnu wọn jọ pọ ni Ilu Oyinbo papa ni nwọn da orişirişi Ẹgbẹ ilu, bi *Conservative Party*, *Labour Party*, *Liberal*, *Communist* ati oniruru Ẹgbẹ miran silẹ nibẹ? Nigbati Dokita Randle koi ti de ilẹ yi rara, ti Peter Thomas ko tilẹ mọ ilu ti o njẹ Eko ri, ti Dokita Ọbasa şi nrojo ni Ikija, ti nwọn koi ti bi Sammy Pearse rara, ti awọn enia Ajasa şi wa ni Ilu 'Dahọmi, ti Herbert Macaulay koi ti de inu aiye, ti awọn aşiwaju Dokita Jones ati Tommy Jackson wa ni Ilu Saro ati Liberia, ni ariyanjiyan ti wa ni ilu. Iyatọ ti o wa ninu edekoyede igbana ati ti isisiyi ni wipe, ika, tẹmbẹlẹkun, anikanjọpọn ko pọ nigbana to ti isisiyi, ajeji ko si ri aye tẹ ilẹ yi girigiri nigbana bi akoko aiye Oyinbo yi. Titi aiye ainipẹkun ni a o ma ri awọn enia atata ti o fẹ ire ilu wọn; titi lai, ẹwẹ, ni a o si ma ri awọn alakọri, alakọra, gẹgẹ-aiya, ti yio ma ra akara gbọkankan lati ri nkan ṣe inawo ọtẹ!

Ẹnikẹni ti o wu ki o le ṣe aşiwaju ninu ọrọ ilu, o ṣoro ki gbogbo ilu to gbọ tirẹ; ki a tilẹ wipe gbogbo ọrọ ti o nsọ ati gbogbo wahala rẹ ni o dun mọ ilu ninu, sibẹsibẹ, a ki yio şai ri awọn ọlọtẹ diẹ ti yio ma wa işubu rẹ; awọn ẹlomiran, ẹwẹ, le ro wipe ọna ti o ngba fi inu nkan rere wa si ilu ko dara to loju wọn; nitorina, awọn fẹ gbidanwo ọna miran fun ara wọn.

Njẹ bi eyi ba ri bẹ nitotọ, irọ ha kọ ni ẹniti o kọ iwe si *African World*, Iwe-irohin Ilu Oyinbo wipe, "ẹnu gbogbo ilu wa ni o ş'ọkan nipa ọrọ ilu" npa? Bẹ gẹgẹ ni o si nparọ, nigbati o sọ wipe, Ijọba pẹlu awọn Onifila-funfun ni o npaşẹ ni ilu, nigbati o şe wipe ninu Igbimọ ti Monsipa (*Municipal Council*,) ninu ti Aşofin ilu (*Legislative Council*,) ninu ti Oşelu (*Executive Council*) Onifila-funfun kan şoşo pere ko si ninu wọn. Nitotọ, Ijọba pẹlu awọn Oloye wa ni o yẹ ki o ma paşẹ ni ilu, şugbọn Ijọba ha fun awọn Oloye wa ni aye rara? Agbedọ!

Eyiti o sọ wipe Ẹgbẹ *Democratic* ti nwọn nṣe ni Ẹhingbẹti ko ṣe tumọ si ede Yoruba, irọ funfun patapata ni ; nitorina ni a ṣe la a yekeyeke ni ede Oyinbo ni ọsẹ ti o kọja, ti a si sọ itumọ rẹ pẹlu wipe, Ẹgbẹ ọpọ enia ti o nwa ire ilu ni o njẹ bẹ.

Esi ti a si fi si Iwe-irohin Ọlọla Kitoyi Ajasa ti ọjọ kẹtala oṣu ti o kọja ni wipe, ti o ba jẹ otitọ ni Ọgbẹni Birrel Grey, Balẹ ilu, *The Resident of the Colony* fẹ lati mọ itumọ orukọ Ẹgbẹ na ni ede Yoruba, njẹ ki on papa sọ itumo orukọ rẹ fun wa, ati orukọ oye ti o jẹ fun wa niti Yoruba ti o ba le ṣe e : titi a si fi nkọ iwe yi, Loya Ajasa, tabi "Akọwe-alagbọn" ti o kọ iwe si Iwe-irohin Ilu Oyinbo, tabi Mr. Birrel Grey, ẹnikẹni ninu awọn mẹtẹta koi ti le dahun ibere wa na.

L'aisi ani-ani, gbogbo isọkusọ ti nwọn nsọ si Ẹgbẹ Tunluṣe yi, nwọn fẹ lati fọ Ẹgbẹ na ni, ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba ro ibi si Ẹgbẹ na lainidi, ofo ni omi ẹfọ nṣe !

"Akọwe-alagbọn" ti o kọ iwe si Iwe-irohin Ilu Oyinbo ti a nsọrọ rẹ yi sọ fun wa wipe, ni akoko owo-omi, ẹhin Ijọba ni Oloye Ọbanikoro wa ; a si já irọ́ rẹ, nitoripe Ọbanikoro papa ko jẹ ki ọrọ ti o sọ akoko na loju gbogbo ilu jẹ pe, "o san ki nwọn di okuta mọ on l'aiya, ki nwọn ju on si alagbalugbu omi ọsa ni Ẹhingbẹtl, ju ki on san Owo-omi lọ !"

"Akọwe alagbọn" yi tun sọ fun wa pe Chief Adamọ Akẹju Ọbanikoro lo gbọn ju gbogbo awọn oloye iyoku lọ, ati pe nkan to jẹ ki nwọn ma jowu rẹ ni pe, oye ti on fun Ijọba, ati ọna ti on tọ wọn si ninu ofin ati aṣa Ilu.

Lai sọ ohunkohun lati rena Ọbanikoro, esi ti awa fi i ni pe, to ba jẹ pe Ijọba jẹ ki nkan wa gẹgẹ bi o ti ni lati wa ni ti ilẹ wa, tani njẹ Obanikoro nibiti a ba nsóro awon Onifila funfun ? nitori ipo Babalawo tabi Onifa Ọba lo wa, ko si si ni ipo ti o le tọ Ijọba s'ọna nipasẹ ofin tabi aṣa Ilu, ki a tilẹ wipe o mọ ọ daradara ; ati pe "akọwe alagbọn" na tile nsọ isọkusọ ni, nitoripe ko sọ sinu iwe na pe nigba bayi, tabi lakoko bayi, ti Ijọba nfẹ lati mọ nipasẹ ofin ati aṣa Ilu Eko yi, Ọbanikoro ni nwọn ranṣẹ si ko wa fi ọna han nwọn.

Olubori isọkusọ ti akọwe alagbọn "na sọ ni pe ile lasan kan ṣa ni ile Eleko, ṣugbon Ọbanikoro lo gbe ngbe *Palace*" Afin.

Iba ma si aiye Oyinbo, iba si ṣe pe a mọ "akọwe alagbọn" na, ogun ni a ba ni ki nwọn fi gb'ẹje l'ẹnu re.

Eyi ti "akowe alagbọn" na wipe ẹniti ọfin ba fi da lẹbi ẹwon lẹkanṣọṣọ bi Horatis Bottomley, ko gbọdọ da si ọrọ Ilu mọ ṣe kelebọ. Ni ilu Oyinbo papa, a ko le ka iye ẹlẹwọn to wa ni ajọ igbimo nla, *Parliament* wọn. Ibaṣe wipe gbogbo ọdaran ni ọwọ ntẹ, tabi ni ọwẹ titẹ ni, enia melo ni iba le pe ẹnikeji rẹ ni ẹlẹwọn l'Eko ? tab Dokita melo ni iba raye dọbalẹ kiri bi ejo

nitori ogun ologun atọdun mọ-dun ti koi ṣe "akonta" rẹ titi di oni oloni. Ọrọ ṣi ku pupọ lẹhin nisisọ. Adaba fọgede o ṣebi ẹiyẹle ko gbọ, ẹiyẹle gbọ, o ṣi ntiri diẹ ni.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

## THE EDITOR'S OBSERVATORY.

### A Street crying for help. Mr. Town Warden, will you help?

Dwellers in a certain part of Griffith Street, Okepopo, to be more precise, those living in the lane by Iya-alabala's— Mr. Paul's mother's house, have a sorry story to tell our Town Warden with regard to the filthy and miry state of the lane, every night due to the dumping of foul water thereon without proper drainage.

We know for certain, that the attention of the Warden need only be called to this, and he will do the needful however tardy.

**"One God, One Law, One Element,**
**One far-off Divine Event,**
**To which the whole creations move":—**

*Tennyson*

The gratifying news is to hand, of the establishment in town, lately, of the **African Unitarian Church**, by a body of devoted worshippers. This is, as it should be. It is also stated that ere long, the general public will be informed of the time and place this Society propose holding their Divine Services.

"Courage, brother, do not stumble,
Though the path be dark as night:
There is a star to guide *The Humble*
Trust in God *and seek His Glory*."

(With Apologies to the Author).

### Mr. D. A. Leigh.

Our respected townsman Mr. D. A. Leigh of H. M. Customs Lagos, is on a three-month leave of absence; with effect from Monday next.

### Arrival of Prince of Wales' Car.

There was a little flutter in the Customs Debt, Marina, on Thursday last, when the Prince of Wales' Car was fixed up after the landing and driven to its destination; the affair attracted the attention of a goodly number of lookers on.

### Thanks, one and all.

Since the publication of our open Letter No 52 of 1925 in our last issue, Congratulations tick ou fa[illegible] have been showered on us in falls-of-Niagara shown.

To one and all we say

Thank you !

## Eko Akete Sunday Discourse.

### AṢARO FUN ỌJỌ ISINMI.

[ Lati ọwọ INAWỌLE. ]

Gẹgẹ bi ẹkọ nipa "Ẹṣẹ nipa Ẹda", olukuluku enia ni Ọlọrun ni lati jẹ niya. Awọn ti o nkọ ni nipa isin-atọwọda sọ pe ọpọlọpọ enia ni ko ni ri iya bayi nitori Jesu ti jiya nitori wọn,—ati pe bi o ba ṣe pe Kristi ko ku nitori wọn Ọlọrun iba ti fi ibukun fun wọn,—ati pe enia ni lati gbẹkẹle ohun ti Kristi ti ṣe fun wọn, nwọn ni lati ma gbadura lorukọ Kristi", nwọn ni lati ma sọrọ rẹ bi ẹniti o ti sanwo fun igbala wọn. Oniruru itumọ ni awọn enia ti o nkọ ni lẹkọ nipa isin fi si ẹkọ isin yi, ṣugbọn gbogbo wọn ni o gbagbọ pe Kristi jiya nitori awọn ẹlẹṣẹ, ati pe a dari ẹṣẹ wọn ji wọn nitori ijiya Kristi. Awọn ti o gba Ọlọrun-kanṣoṣo gbọ ko gba iyi gbọ.

Gbogbo ẹkọ-isin ni o kun fun aidọgba ede, nwọn ko si ba ara mu, nwọn ko si lọ nipa ogbọn tobẹ ti ẹkọ rẹ le fi ye ẹnikẹni ti o le ronu jinlẹ pe ẹkọ ki iṣe otitọ. Nwọn sọ fun wa pe Baba kan wa ti o jẹ Olotitọ ti o fẹran enia, o da gbogbo ẹda rẹ ni ẹni buburu; ati pe nipa ẹda ti o fi da wọn, O ni lati ran wọn lọ sinu iya ailopin; pe nwọn ko le bọ ninu iya buburu yi nipa agbara wọn; pe ọna kan ṣoṣo ti a le fi gba diẹ ninu wọn la ni pe ki Ọlọrun ki o wa ni awọ enia ki o si jiya lori agbelebu; pe nitori iku ẹnikan ti ko ni ẹṣẹ ni a o ṣe dari awọn ẹlẹṣẹ ji wọn; ati pe bayi ni a o ṣe da awọn ẹlẹṣẹ si, nitori ẹniti ko ni ẹṣẹ kan ti jiya ti ko tọ si i lati jẹ. Ero ti o wa ninu ẹkọ yi o jẹ eyiti o kuru pupọ. Ẹkọ-isin yi sọ fun wa nipa Ọlọrun ti o si jẹ Olododo pe o njẹ enia niya bakanna lai jẹ pe oluwa rẹ dẹṣẹ; Baba oninure ti o ni itẹlọrun si ẹjẹ alaiṣẹ; ko fẹ iwa rere enia, ko si fẹ ki olukuluku enia ki o ma sa ipa ara rẹ. Ẹkọ nipa Etutu fun Ẹṣẹ papa ti o kọ ni pe awọn ti o dẹṣẹ ko ni jiya ẹṣẹ wọn nitori ẹnikan wa ti ko dẹṣẹ ti jiya nitori ẹṣẹ wọn ko ba iwa otitọ mu ati ododo pẹlu.

Baba wo ni o wa ti ọkan ninu awọn ọmọ rẹ ma ṣẹ, ti o si fẹ bawi ti o si ma jẹ ki ọmọ na lọ lai jiya eyiti o tọ si i, nitori ọmọ rẹ omiran nfẹ ki a jẹ on niya dipo ẹniti o ṣe gan? Olori Ọlọpa wo ni o ma fi ẹniti o dẹṣẹ tabi ti o ru ofin silẹ lai jẹniya, nitori ọmọ Olori-Ọlọpa sọ pe ki baba on jẹ ki on lọ si ile ẹlẹwọn dipo ẹniti o jale? Onidajọ wo ni o ma ni ki apania ki o ma lọ pada si arin enia, nitori ẹniti ko pania kan sọ pe on fẹ ki a pa on dipo ẹniti o pa enia? Bi ododo awọn enia ko ba jẹ ṣe bayi, kọ yẹ ki a ma ro pe Ọlọrun jẹ ṣe bayi. Nibo ni a fi ifẹ Ọlọrun si, ti a fi sọ pe o nṣe ohun kan fun enia ti o jẹ anu rẹ ti ko nipẹkun ko jẹ mu U ki o ṣe irufẹ nkan bayi, nitori Kristi ti jiya fun awọn enia ti o dabi ẹni pe iya jijẹ jẹ ohun ti o dun mọ Ọlọrun ni inu, ati tita-ẹjẹ silẹ jẹ ohun ti o fẹran pupọ. Bi o ba ṣe jijiya fun ẹlẹṣẹ ni o mu ẹṣẹ wa, a le mọ pe eyi jẹ ikilọ nitori ẹṣẹ; ṣugbọn bi o ba jẹ pe ẹniti ko dẹṣẹ ni a ma njẹ niya, eyi ko ṣe rere kan fun ẹnikankan arara, nitorina idarijin yi yio ma mu ki awọn ẹlẹṣẹ ma ṣe buburu siwaju ati siwaju nitori nwọn ni ẹniti o ma jiya ẹṣẹ wọn. Ẹkọ ti "Etutu fun Ẹṣẹ wa" ki iṣe otitọ nitori, (1) O lodi si ododo ati ifẹ Ọlọrun; (2) Ko ba ero-ori wa mu nipa iya ti enia ma jẹ; (3) O nkọ enia lati ma jẹ ki nwọn ma huwa rere nitori nwọn ma ro pe nwọn le dẹṣẹ, nwọn ko si ni jiya mọ.

Ẹsi ti awọn enia ma fi ni eyi—Sibẹsibẹ, a ri ẹkọ nipa "Etutu fun Ẹṣẹ" ninu Bibeli. Ṣugbọn ẹkan ni a ri ọrọ yi ninu Majẹmu Titun ti ede Gẹsi (Romu ori 5, Ẹsẹ 11), iru ọrọ yi ti a lo ni ede Greeki tun wa ni ẹṣẹ omiran ti itumọ wọn jẹ "Ibadapọ" (Wo Romu ori 9, Ẹsẹ 15, Korinti Keji ori 5, Ẹsẹ 18, ati 19). Bibeli ti a tumo tabi ti a tun kọ lo "ıbadapọ" dipo "Etutu fun Ẹṣẹ." A fi Enia ati Ọlọrun ha bi ẹniti a dapọ, awọn ẹniti nwọn ti wa lọtọtọ, ṣugbọn ti Kristi si da wọn pọ.

*(Ko ti Pari.)*

---

### AN ORATION ON DADA ADESHIGBIN BY PROF. DENIGA.

Professor Adeoye Deniga's oration on Dada Adeshigbin delivered at Ilupesi Hall on the 3rd instant was a masterpiece. It is the product of ripe experience the Professor being on the job of lecturing for over a period of 20 years. The oration encompassed all angles of region: the philosophic. Scientific, Psychologic and Metaphysic. It is purposely saturated with gleanings from eminent writers such as Seneca, the Greek philosopher, the immortal Shakespeare, Milton, Long Fellow, &c., &c. We have the life of the hero portrayed to us with the clear perspicuity from the cradle to the grave.

An eventful life pregnant with great achievements but void of pomp and show, an ostentations and hypocritical parade of self, a life purely imbued with racial interest but lacking in bigotry. It is a normally blended life guided by the motto "Fear God, Honour the King, Respect all men." As an emblem of true Patriotism, a true Christian and a true Man, Mr. Adeshigbin's name will go down to prosterity and with his name will be coupled that of Prof. Deniga the Bard who immortalised his name.

This is an instance that we could confidently apply the Shakespearean dictum.

"His life was gentle, and the elements
So mixed in him, that nature might stand up
And say to all the world, "This was a man"

The large audience that heard the oration were unanimous—the expressed desire to have it printed and widely circulated both—English and Yoruba.

Mr. Ayo Ajala A. Mus. V.C.M. (Lond.) deserves congratulation for the impressive dirge written for the occasion and which was efficiently rendered.

To Mr. H. S. A. Thomas also, the Chairman of the evening who blended the oration to perfection with his rare critical intellectuality, we say "Bẹ bẹ ni ki a ma ri o."

H. ANTUS WILLIAMS.

## *Stop Press!*

*Friday 6th inst. at about 12.23. p.m.*

REX *Versus* DR. SESI KAPO AND ALBERT TAIWO.

Court, found two accused guilty of the charge with which they were charged Fraud: Sentence, 1. Dr. Kapo fined £50 or 6 months. 2. Albert Taiwo, £25 or 3 months.

Conviction appealed against by the learned Leader of the Bar The Hon J. Egerton Shyngle: leave granted: grounds of Appeal "filable" within 4 days.

*Eko Akete*—Wireless.

---

[ *Copyright* ]

## "EKO AKETE" LAW REPORT.

[ Lati ọwọ ATOLUGBOKUN. ]

IROHIN ILE ẸJỌ NIWAJU ỌGBẸNI H. S. BERKELY NI IJỌ *TUESDAY* IJỌ KẸRINLELOGUN OṢU *FEBRUARY*, 1925.

*Charge No*. 366. Taiwo ati Aina wọn bara wọn ja ni ita gbangba Adajọ ni ki wọn san ṣile meji abọ ẹnikọkan.

Ni ijọ *Friday* ijọ kọkandilọgbọn oṣu *February 1925*.

*Charge No. 398*. M. A. Alabi ẹniti Ọlọpa mu fun ẹsun wipe olu ọmọ to nkiri *Kerosine* ti orukọ rẹ njẹ Sunmọla—Adajọ da silẹ nitori ọrọ na ko lori.

*Charge No. 326*. Rahimi ọmọ jaguda Ọlọpa mu fun ẹsun wipe oji iṣasun ọbẹ pẹlu ẹbẹ inu rẹ Adajọ wo titi oda silẹ oni ko ma lọ.

*Charge No. 397*. Ajai Musun ẹniti Ọlọpa mu fun ẹsun wipe oji agogo apo (*Pocket Watch*) ti ọrẹ rẹ Charlie Asure ti 141 ita Bamgboṣe nigbati ọrẹ rẹ loki ti gbewiri yi ni on fẹ mu omi ki Charlie to bu omi de, ọfọn ti wọle, o ti ki ọwọ bọ apo o ti yọ ago. Ọdaran yini Charlie jẹ on lowo o si fi agogo di owo na. Adajọ da sẹria fun o ni ko si lọ si ẹwọn oṣu kan pẹlu iṣẹ aṣegan.

"A LE GBELE GBỌFA LAI R'OGUN"

*Charge No. 391*. Ọlọpa mu Ọgbẹni Coker fun ẹsun wipe o gbe ita gbangba ka ma ju oko biriki sile ni ọgba *Cinema*, ti Oshodi ni Ẹpẹtẹdo nigbati wọn nṣe ere *Cinema*, irufẹ iwa bayi o dun Adajọ o si ni ko san ogun ṣile tabi ẹwọn oṣu kan.

*Charge No. 293*. Ọlọpa mu Almi Salami fun ẹsun wipe ko gba iwe si *Motor* rẹ Adajọ ni ko san ọgbọn ṣile.

*Charge No. 294*. Ọlọpa mu Ernest S. Ikoli fun ẹsun wipe ogun *bicycle* lai tan ina si. Ikoli ni on ko jẹbi Adajọ ni nitori kini, Ikoli ni Ọlọpa ni lati pe on ko sọ fun on wipe ina atupa on ku Adajọ ni iyẹn loro wipe o jẹbi, Adajọ ni on fi eyi fa leti ko ma lọ.

*Charge No. 290*. Yesufu Ijaọba, Ọlọpa mu fun ẹsun wipe ko gba nọmba si *Motor* rẹ ati pe *Motor* rẹ ko ni iwe Adajọ ni ko san adọta ṣile.

*Charge No. 371*. Awọn Oyinbo meji Fred Harris ati Hobart Ọlọpa mu wọn fun ẹsun wipe lẹhin ti awọn Oyinbo yi mu ọti yo tan wọn ko lọ si inu ọkọ wọn, wọn lọ ya *Peace Hotel* wọn de bẹ obinrin to nṣe *Hotel* ti sun nigbati awọn ẹlẹgiri meji na jade wọn si fọwọ kọ apẹrẹ ati abẹbẹ (*Basket and Fans*) ti Ọgbẹni Ernest Farmer Ọgbẹni yi ni ilura si wọn bo ti yoju loke pẹtẹsi bẹ lori lọwọ wọn o si ni ki wọn ko fun on awọn ara bi taku ibẹ lo ti di ti Ọlọpa. Awọn Oyinbo yi ni awọn ko ranti ohun to ṣẹlẹ. Adajọ ni ki wọn san poun marun marun tabi ẹwọn oṣu kọkan ki poun marun bọ si apo Ijọba ki Ọgbẹni Farmer gba poun marun fun nkan rẹ to nu.

*Charge No*. 325. Adeline Thompson pe ọkọ rẹ Jonathan Binuyọ Thompson lẹjọ fun ẹsun wipe o lu on la lu bo lẹ. Adajọ fi ẹjọ yi si ijọ kẹtadilọgbọn oṣu yi ara Adeline Ẹbun Thompson ko da iyẹn ni ko jẹ ko yoju si Kotu.

Surakatu Ijaọba ẹniti Ọlọpa mu fun ẹsun wipe o yọ ọbẹ si Ọlọla Joseph Egerton Shyngle ni ile rẹ. Ọdaran yi ni ki Adajọ ba on bẹ Ọlọla Shyngle ko jowọ. Shyngle bọ sinu apoti o rojọ; akọwe Shyngle fi orukọ rẹ njẹ Yesufu Adeọla Oki bọ si inu apoti o fọ pẹrẹpẹrẹ ọrọ. Adajọ ni ki Sura fi ọwọ siwe ogun poun wipe on ko ni ṣe bẹ mọ ọpẹlọpẹ Shyngle to bẹ Adajọ wipe ko ma sọ s'ẹwọn: bi ko si iyẹn ni, Ọgba onigo ni Sura iba ma sọrọ.

Emi ni tinyin nitọtọ,

ATOLUGBOKUN.

---

### EKO HIGH SCHOOL.
### LAGOS.

The following candidates have been successful in the College of Preceptors Certificate Examination held in December 1924.

Junior:—Abdul Wahabi Fanimokun

Preliminary:—Liamidi A. Abibu
Joseph M. Shyllon
E. Amosu Johnson
Charles Ladipo Roberts
E. Adewale Deniga
Jonah I. Okunna
A. Olufolakan Lapite
Gabriel O. Kasumoko
Samuel D. Borocasikun
Fredk. A. Williams
Bolu Oki

W. B. [illegible],
*Principal*

Lagos,
6th March, 1925.

### EWO NI TI ABARA-MORE JẸ, OKU-ONIGBESE TI NG'OGI ỌRUN?

"Ọrun ki wọ'we" ni ede ẹnikan ti a gbọ pe "ẹru Ọlọrun ọrẹ rẹ kan gbe ọdunrun poun (£300) fun ṣan-di fun rira *cocoa* fun on lati nkan bi ọdun meji sẹhin: ninu eyiti ọrẹ to ni owo yi ko f'oju ganni ẹvọ eso *cocoa* kan ambọsibọsi apo *cocoa* lọdọ ẹdẹlẹsinrin yi: bi a f'ejila ran'mọ ni'dun l'Ajaṣẹ, b'a o rowo ẹni, ko ha yẹ ka ri idun ẹni bi?

A tilẹ tun gbọ pe ọrẹ oninure yi ti fi igba kan duro ẹgbã pọun (£2,000) lọdọ olowo kan fun ọrẹ rẹ maṣe'gilore na ṣugbọn titi di oni, ọrẹ yi fa ekeji rẹ na fun owo olowo ṣugbọn ko ni iru. Ẹnyin Ọkawe wa yio niran ohun ti a sọ laipẹ yi sinu *Eko Akete* nipa iwa arigid'enia ti awọn ẹlomiran nhu lọna bayi; irufẹ awọn abaramoreje wọnyi lo nmu awọn *ọmọ-gutter* ati awọn ọmọ-orulesọmi ninu awọn Oyinbo ma kọ'we kobakungbe irufẹ eyi ti Oyinbo ti o npe ara rẹ ni F. A. Day tabi **F. A. Night** kọ sinu Iwe-irohin ***African Messenger*** ti ọsẹ meji sẹhin, eyi ti Oyinbo na f'ori jona ti o si ghorun ara rẹ lọdọ wa, nipa esi iwe to kọ na, ti a tẹ sinu ***Eko Akete*** ti ọsẹ to kọja.

Ṣugbọn ara alanpọ lo pọ si t'elepo diẹ!!!

---

### IGBẸ L'OWO WÀ.

#### EKO.

Bi ọwọ Ekurọ, Epo ati *Cocoa* ti ku si lọsọ yi leyi:—

EKURỌ

£15 0 0 fun *ton* kan.

EPO.

£28 0 0 fun *ton* kan.

COCOA.

£28—£29 fun *ton* kan.

#### KANO.

GROUND NUT.

£12 5 0.—£13 0 0 fun *ton* kan.

---

## Thanks for Sympathy.

Mr. Ebenezer Craig begs to return thanks to all friends at home and abroad who have, by telegrams, letters or otherwise sympathised with him in the irreparable loss which he sustained recently of the death of his late dearly beloved wife, Mrs. Mabel Aina Craig, which sad event occurred at Akure, Ondo Province, on the morning of the 24th of February, 1925.

"On that happy Easter morning,
All the graves their dead restore;
Then my dearest MABEL will I,
See once more."

---

## *Thanks for Sympathy.*

Mrs. Adelaide L. Davies-Johnson, Mr. Josiah Akinwande Thomas and Miss Regina Oyinkan Thomas on behalf of their family beg to return their sincerest thanks to all kind friends, acquaintances at Lagos and abroad who by calls, letters or telegrams have expressed sympathy during their recent bereavement of the home-call of their brother Edwin Sobowale Thomas, Government Dispenser, at Enugun Hospital, on Thursday the 19th of February, 1925.

---


## THE CITY ACADEMY.

The Rev. J. A. Leigh, M.A., has [illegible]reet, recently established at 34, Pike St[illegible]ge of Lafiaji, an academy for the advant[illegible]uca- those desirous of higher standa[illegible] edu- tion; for prospectus, etc.

Apply to:-

J. A. LEIGH,
*Principal.*

---

# TO LEASE.

# A House

AT 4[illegible] AROLOYA STREET,
FOR [illegible]ARTICULARS APPLY TO:—

***Asani Abasi,***
16, Willoughby Street, Lagos.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASỤ ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)
Masses Isin Arọ,
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.
(EVENING.)
(Benediction) Isin Ibukun,
4.45—5.30 6.45—7.30.
ST. MICHAEL'S ) Lafiaji.)
MORNING. 7—8 8.30—9.30
EVENING. 5.45—6.30

**ANGLICAN**

| Time. | Preacher |
|---|---|
| 9 a.m. Christ Church. | The Vicar |
| 6.30 p.m. do. | do. |
| 9 a.m. St. Paul's (Breadfruit) | Rev. S. V. Latunde |
| 6.30 p.m. do. | The Curate |
| 9 a.m. St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. do. | do. |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. St. Peter's (Alapako) | |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev S. J. Gansallo |
| 9 a.m. St. David's (Jordan) | Rev. J. H. Ogunro |
| 6.30 p.m. do. | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | Rev L. R. Potts Johnson |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. D. A. Bababunmi |
| 7 p.m. | do. | Bro. C. B. Williams |
| 10.[illegible] a.m. | Olowogbowo | Rev. A. N. Cole |
| [illegible].m. | do. | Rev. D. A. Bababunmi |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. E. E. Ajoṣe |
| 7 p.m. | do | Rev. S. A. Pearse |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Bro. T. K. Aderin. |
| 7 p.m. | do. | Bro. Ọlaboye Laleyẹ |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Mẹta) | do |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. T. A. White. |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. I. O. Oyekunle |
| 6.30 p.m. | do. | Bro. E. O. I. Onitiri |
| 9 a.m. | Zion | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 9 a.m | Salem Church (Ebute Mẹta) | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 9 a.m. | Bethlehem Church (Ebute Mẹta) | |
| | do. | |
| 10. a.m. | African Methodist | Rev. N. J. D. Ṣomuji |
| | do. | Bro. E. A. Williams |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

10.30 a.m.
6.30 p.m. Rev. J. R. Williams.

**(EBENEZER BAPTIST)**

9 a.m. Rev. E. C. Alabi
6.30 p.m. do.
9 a.m. Ararọmi (Baptist)
6 p.m.

**ISOLARIAN BROTHERHOOD.**

7.30 a.m. Ilupesi
7 p.m. The Founder.

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Rev. B. A. Wifunkẹ.

**AHMADIA (ISLAM.)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe
(Central Mosque, Arọlọya Street.)

**ZION CONGREGATIONAL**

9 a.m. Kakawa St. Locum Tenens.
7 p.m. do. do.

**SALVATION ARMY**

10 a.m. Glover Memorial Hall
Staff-Captain & Mrs. Wilson
7 p.m. do.

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square,
Wm. C. T. Terrell.

---

### ỌMỌ OKUYANMUYANMU.

Gbogbo awọn ọmọ Oloye ni Eko ati agbegbe rẹ lo npejọ si Ilupesi Ẹnu-ọwa, ni ọ'jọ Satide Satide lati ma gbero ohun ti yio jasi idagbasoke ilu wọn.

Ẹnikeji, o ti fi orukọ silẹ nibẹ bẹ? Owo kọ ni a fi nwọ ẹgbẹ yi, ọla ni, o ni ipo ninu ẹgbẹ yi, niwọn ti o ba ti jẹ ọkan ninu ọmọ oye wọnyi.

1. Akarigberi
2. Ọgalade
3. Idejọ
4. Ogboni Olorogun

"Ire ilu rẹ ni ki o jẹ ẹdun ero rẹ"

JAMES ỌLADIPỌ HOTỌNU
DAVID AJE OGUNLANA
*Awọn Akọwe Ẹgbẹ.*

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "Excelsior" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ikole fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn oniṣowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKẸ Oniṣowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanṣọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Iṣika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ti Ọṣan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-ṣawa Okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ṣọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Ọlowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Ohun-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

### Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at Kessler's Establishment, 7, Labinjo Lane, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

ẸNIKEJI,

Aṣọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Ẹmọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku owo wọn, lọ bere ni 3, St. John *Street,* Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

### GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same,* if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

**Cable Address:—**
"Steinafrik" HAMBURG

**E. H. STEIN & Co.**
**HAMBURG, Neurwall 16/18.**
**Hildebrandhaus.**
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

**Ruby Plates! Ruby Plates!!**
**Ruby Plates!!!**

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from :—

DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.

# A. Kessler,

7, Labinjo Lane,

Williams Street,

**P.O. Box 459**

Highly Recommended :

THE

# Pilsener Beer

*"Crystall" Brand*

*Light & Sparkling*

**Per Case**

**33s.**

**Send for a trial case to-day and convince yourself of the first quality of this Beer.**

GBOGBONIȘE FUN OBINRIN

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, iju, Ẹd
Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ ati orișiriși arun
ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

"SHAKE THE BOTTLE."

A nta Egbogi yi ni Ṣabu Egbogi Ogbẹni V
White, 41, Offin Road, Lagos.

WO'BI ẸNIKEJI,

Oniruru Posi li o wa fun tita; lọdọ Pa
I. Samuel owo wọn bẹrẹ lati Pọun me
abọ titi de Pọun mejila gile mejila. Ẹ
ri wọn ra ni 40, Campbell Street, le
Ile-isin Ṣọṣi Ebenezer; ati ni No. 7
Igboșere Road, nitosi *King's College*.

**Ile Ita Egbogi ti Macaulay,**

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orișiriși Egbogi lo șẹșẹ de
wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orișir
ogun Ẹda, ogun arun așiri, ogun Arẹn
ogun Onigbameji, ogun Aran orișiriși, og
Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko
mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si j
idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo
ti a gbe nta wọn.

***Register Now!***

For the evening classes now forming
the Rose Thomas School of Embroide
55, Broad Street, we teach :—

Embroidery, Milinery, Flower Mak
Fancy Work, Dress Making.

5 week days, Monday to Friday—fr
4 p.m. to 6 p.m.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.